**Grace Jones**

*láti Ọwọ́ Irenosen Okojie*

*Tí Kọ́lá Túbọ̀sún túmọ̀*

Nígbà tí ìyapa ara ìran jíjóná kan ti bá ara rẹ̀ wọ inú ibùsùn, pẹ̀lú etí olókuta oníksì tó ń dán, tí àwọn ère aláìníràántí ti sọ orí ayọ́ wọn nù sí òwúrọ̀ tó ń bọ̀, tí òun sì ti tẹ ojú rẹ̀ mọ́ ààyè tó wà lábẹ́ ilẹ̀kùn, tó ń sunkún, tó ń nàgà fún erùpẹ̀ ìkúnwọ́ tí a ò tíì lò rí fún ìṣaralóore, ilé iṣẹ́ pè, Hassan ní pàtó. Ó ti fojú sun oun tó fẹ́ ṣe lọ́jọ́ náà sí oun mẹ́ta tó dájú ṣáká, sóríi rìsíítì rírún kan ti aṣọ òtútù Roland Mouret aláwọ̀ iná-ilé-ijó tó ti wọ̀ lẹ́ẹ̀kan ṣoṣo. Ṣùgbọ́n fóònù dún pẹ̀lú ariwo yeye tó wọra tó sì yọnilẹ́nu. Láì kúró nílẹ̀, tí pàkó náà ń tutù mọ́ọ lára, ó rákòrò lọ sí ìdí agbohùn fóònù, bíi pé wọ́n so ọwọ́ àti ẹsẹ̀ è mọ́ okùn kan lááárín agbedeméjì ayé, tí okun náà sì ń kákò tó sì ń kọlu gbogbo oríṣi ìpele ayé ẹ̀. Ó ro gbogbo ọ̀nà tó fi lè dá gbogbo àtubọ̀tán kọ̀ọ̀kan orí rìsíítì yìí dúró. Ó lè gbéemì, kó dúró de bó ṣe máa jẹrà nínú ikùn ẹ, bí ásíìdì ṣe ń mu gbogbo àwọn ọ̀rọ̀ yẹn tó fi máa dòfo. Ó lè yàá nígbẹ̀ẹ́ jáde. Ṣé o lè ya bébà jáde nígbẹ̀ẹ́? Eléyìí á tiẹ̀ lè fihàn bó ṣe jẹ́ gaan: òburẹ́wà. Tàbí kó tiẹ̀ sọ̀ọ́nù sí inú ilé níbìkan. Kó má jẹ́'ta. Dájúdájú, kó má jẹ́ ìta. Á tiẹ̀ fi sọnù pátápátá báyẹn. Á ní láti tún yẹ àwọn ọ̀nà àbájáde yẹn wò lẹ́ẹ̀kansíi, fi àwọn mìí kún-un, gée kúrú. Ṣíṣe èyí ti mú ọpọlọ ẹ̀ rẹ̀wẹ̀sì mọ́júmọ́, ọkàn ẹ̀ ń jò jáde láti inú iho kọ́kọ́rọ́ iyàrá, tó ń dún bí ẹni tí ó ń fa nǹkan mu bí ọwọ́ ẹ̀ ṣe ń yọ́ bí òrí. Á ní láti sọ rìsíítì ọ̀hún nù sínú ilé ni. Eléyìí á fún-un ní ànfàní láti sún ààlà ìgbà síwájú, bótilẹ̀jẹ́pé ó ní egbò nínú tó fẹ̀ẹ́ tóbi tó òkuta àjà ilé. Nínú ọkàn ẹ̀, olùyàwòránilé jẹ́ Ọlọ́run. Ó ti gbé òkuta àjà ilé sí inú àyà ẹ̀. Níbẹ̀rẹ̀, ó ti yàá ní oríṣiríṣi igun, tí ìlà búlù iná ẹ̀lẹ̀tíríkì ń fún-un ní ìtanijú oríṣiríṣi láti inú ìṣẹ̀lẹ̀ kannáà. Gbogbo ìgbà ló ń dìde. Gbogbo ìgbà ni ó ń mọ̀lára wíwúwo bí òkuta àjà ilé ọ̀hún ṣe ń tàkìtì nínú òfurufú.

Ó gbé agbohùn fóònù s'ókè, ó dìímú digbí, bíi pé kò fẹ́ kó jábọ̀ lọ́wọ́ ẹ̀ bí àwọn nǹkan ti ṣe ń ṣe lẹ́nu ọjọ́ mẹ́ta yìí. Fún ìṣẹ́jú ààyá díẹ̀, ìdákẹ́jẹ́ẹ́ wà lódì kejì. Ó mọ̀ pé Hassan ni. Oun ló

máa ń dúro fún àsìkò díẹ̀ kó tó sọ̀rọ̀, bíi pé ó ń fún ẹ ní àsìkò díẹ̀ láti farabalẹ̀ sínúu ààyè mìíràn. Kìí sọ orúkọ ẹ̀. Ó máa ń rò pé wàá ti mọ̀. Òun náà sì máa ń mọ̀ ní gbogbo ìgbà.

*Sidra, ó dàbíi pé patí kan wà lálẹ́ yìí. Oò ní láti wá, ṣùgbọ́n ó lè dù o. Ọkùnrin yẹ́n jẹ́ olólùfẹ́ Grace Jones gidi. Mo ti tẹ àdírẹ́sì ẹ̀ sí orí fóònù ẹ. Ṣẹ'un tóo máa ń ṣe. Tóo bá ní ìyọnu, pè mí. Sogbó?*

*Mo gbọ́*

Ó fẹ́ẹ̀ sọ fún-un nípa olùyàwòránilé nígbà yẹn. Ó ríi pé òun máa ń fẹ́ ṣeé ní àwọn ìgbà tí kò ròtì. Dípò ìyẹn, ó gbé agbohùn fóònù sílẹ̀, tí ọwọ́ ẹ̀ sì ń gbọ̀n. Ó yẹ orí tábìlì wò fún rìsíìtì. Ìyẹn ti jábọ̀ sílẹ̀ lẹ́gbẹ̀ẹ́ ẹrọ amúlégbóná-tutù, ó tiẹ̀ tí bẹ̀rẹ̀ sí ń sọ ara ẹ̀ nù. Ó ti gbàgbé láti sọ fún Hassan pé òun ń ronú láti máa lọ sí kílásì ìrọ̀lẹ́ lẹ́ẹ̀kan lọ́sẹ̀. Báyẹn ni wọ́n ṣe rí, wọ́n ń fi àìmọye nǹkan sílẹ̀ láìsọ. Kò bèèrè lọ́wọ́ ẹ̀ rí nnkan tí ọmọ Faransé Aljéríà ń ṣe ní Lọ́ndọ́nù tó ń ṣadarí ilé iṣẹ́ afarajọraẹni, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ìyẹn náà ò dẹ̀ bèèrè oun tí ọmọbìnrin láti Martinuque pẹ̀lú ìwé ẹ̀rí ní ẹ̀kọ́ ọ̀tẹlẹ̀múyẹ́ ń ṣe gẹ́gẹ́ bíi afarajọ Grace Jones — ìdàkejì ara àwọn méjèèjì tó ń kọjú sí wọn ní kẹ́lẹ́kẹ́lẹ́ láti òdìkejì ìlẹ̀kùn tó ń yípo.

*Ilé kan wà tó dúró bí ahá: bíi òkúra dúdú fafa bí èèdú tí a ti fà ya láti inú síta. Òkúra náà farati àwọn ọ̀run bíi èhónú fún gbogbo àwọn ìpàdánú ẹ̀, fún ojú sánmọ̀ inú ẹ̀ tí a ti fi àbáwọ́n kàn pẹ̀lú ìka ọwọ́ọ ìtòwọlé ìgbẹ̀yìn ojúmọ́ kan, ẹbọ àwọn ọmọ ará ayé. Ṣùgbọ́n bí ayé ṣe ń sùn, tó ń jí, àwọn ìlú ń kùn pẹ̀lú dàrúdàpọ̀ àti ìtò-lọ́wọ̀wọ́; àwọn odò bẹ̀rẹ̀ láti inú àpò olówùú tó ń di ìgbọ̀nwọ́ oníjẹ́jẹ́ mú; àwọn omi ń ṣàn sókè-sódò sínú ìwògbè tó ti sọnù; àwọn òrìṣà ń yọ̀pọ̀rọ̀ nínú àwọn àwọ̀ láti orí òkun; agbedeméjì ayé gbọn ara ẹ̀ nù díẹ̀; àwọn ìràwọ̀ ń tàn yanyan ní ìdàpọ̀ aláìlétò; àwọn òkè tó fi atẹ́gùn ọyẹ́ tó kọjú si ibi tí àwọn èèyàn fẹ́ bora; ilé náà dúró, bí ìfun àtọwọ́dá tí ìmọ́lẹ̀ orísìrísì ń wẹ̀ fún, tó ń gbé nínú orísìrísì ìpele ọjọ́. Ilé yìí jẹ́ ihò òfifo nínú òkúra nínú ahá nínú ayé láàárín àkójọpọ̀ ìràwọ̀; àwọn àpótí onígun orísìrísì ìwọ̀n nínú ara wọn níbi tí ẹ̀bùn ti jẹ́ irúkannáà, tí a máa ń so mọ́ ìdí tó ti yọ*

*sọnù. Lóríi àjà kọ̀ọ̀kan ahá yìí, Sidra ń sáré sẹ́yìn lọ sí ọ̀sán ọjọ́ kan. Wọ́n ti kìí ní pẹlẹbẹ sínú àpótí pálí tí a fi sẹlotéépù lẹ̀ pa. Lórí àjà kọ̀ọ̀kan Sidra bó àwọn sẹlotéépù yìí kúrò, èyí sì ń dún bí ìfàya nínú atẹ́gùn tí a ò le rí ìlà ẹ̀. Ó yọ àwọn oun tó wà nínú àpòtí yìí. Ìrọ̀lẹ́ ọjọ́ yìí ni a ṣe pẹ̀lú àwọn èròjà tí a fi ń ṣe kéèkì: ẹyin, ìyẹ̀fun, bọ́tà, ṣúgà, bébà fàdákà, oun ìròpọ̀, fànílà.*

*Lórí àjà kọ̀ọ̀kan Sidra sáré lọ̀ sí ibi fèrèsé níbi tó dúró sí nínú aṣọ tó ṣe pẹ̀lú bébà fàdákà.*

*Lórí àjà kìnní, ẹyin ló dà bora, tó ń pariwo.*

*Lórí àjà kejì, ìyẹ̀fun dà bòó, tó ń kigbe tòò.*

*Lórí àjà kẹta, inú bọ́tà ni a rìí sí, tó sì ń yòrò bí ooru ṣe ń mú síi, bí ohun ìròpọ̀ ṣe ń dún pẹ̀lú ìbẹ̀rù lẹ́gbẹ̀ẹ́ ẹ̀.*

*Àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.*

*Orin Grace Jones “La Vie en Rose” ń dún lọ lórí rẹ́díò tí wọn ò tiẹ̀ so mọ́ iná.*

*Dípò ẹ̀, okùn iná náà fò wá láti ìsàlẹ̀ ilé, bíi gbòngbò ẹ̀létíríîkì tí kò ní orísun.*

*Ahá yìí gbọ̀nrìrì.*

*Lórí àjà kọ̀ọ̀kan, Sidra mú oun àròpọ̀. Àwọn ìran tó ti sọnù jábọ́ láti ara fèrèsé; omi ò tó. Àwọn rọ́bà afami ń gbọ̀n pẹ̀lú agbára àti ọkàn ẹlẹ́dùn; tàkúté ikú, àwọn ilé àjá ti há sọ́nà lẹ́ẹ̀kansíi, tí wọn ń bi aṣọ àwọn panápaná bíi kòkòrò ńlá àfọwọ́dá. Bíi ìwé jẹ́nẹ́sísì tó ń sáré lọ, gbogbo nǹkan dàrú lójijì. Àwọn eérú kórajọpọ̀ sí irú àwọn ènìyàn tó ń rákòrò lójú ọ̀run kí wọ́n tó kọlu àwọn ọkọ̀, tó tún pa wọ́n run lẹ́ẹ̀kansíi.*

*Agbedeméjì ayé di ìdáméẹ́rin.*

*Iná dìdé sókè.*

*Ìdí àwọn àpótí wọ̀rọ̀kọ̀ yìí gbaná jẹ.*

*Àwọn ìdọ̀tí wá di ẹ̀yẹ iná tó ń rìn lọ.*

*Kókó kékeré kan hàn láàárín àwọn àkójọpọ̀ ìràwọ̀.*

*Olùyàwòránilé mú iná kan dání lọ́nà tó dàbí igi òjé, bíi irin iṣẹ́ tó le paradà nígbàkugbà.*

Sidra ti kọ́kọ́ rí Grace lórí TV. Ó ní láti jẹ́ bí ọmọ ọdún mẹ́tàlá nígbàyẹn. Nígbà yen, o ti ń sáré lé Carla àti Dorian tí wọn ń fi skurudẹ́rẹ́bà seré lẹ́yìn àga, tí wọn ń lò síwájú-sẹ́yìn bíi pé wọ́n ń ṣeré idà. Wọ́n ń pariwo “En guard” lẹ́ẹ̀kọ̀kan, wọ́n sì ń mú skúrùdẹ́rẹ́bà ọ̀hún dání bíi idà tí a fi ọnà gbẹ́. Ẹ̀rọ ìfọṣọ ń yí lóbìírípo. Àwọn fèrèsé wà ní ṣíṣí sílẹ̀ láti fi ẹ̀rí oúnjẹ ilá tó sè, ṣùgbọ́n tí kò sè dáadáa, pamọ́. Ẹ̀rọ ìbòsí èéfín ti bàjẹ́. Ọgbọ̀n ìṣẹ́jú sẹ́yìn, ó ti ń dún lemọ́lemọ́. Nínú ọ̀nà ìbínú tó gbà láti múu dákẹ́, ó ti bàájẹ́ pẹ̀lú ọwọ̀. Ṣùgbọ́n kò sí èyí nínú èyí tó ṣe pàtàkì nítorípé obìnrin tó fojú jọ̣́ ẹ̀ wá nínú ẹ̀rọ TV. Èrò kan tí kò yée ń fàá lọ sójù ìwòran náà, òun náà sì tẹjú mọ́ọ. BBC1 ni. Kò tî rí obìnrin aláwọ̀ dúdú tó dúdú mirinmirin báyìí lóri ojú ìwòran rí. Èyí rẹwà gidi, kò sì lè gbójú kúrò.

Obìnrin náà tó ga, tó wunilójú tó dàbí ará ayé mìíràn, tó sì ní ìgboyà wọṣọológbò dúdú kanlẹ̀. Ètè ẹ̀ ní àwọ̀ pupa irú ọkọ̀ panápaná, orí ẹ̀ wà nínú aborí olófefèé tó dàbí ilé oyin. Sidra ń lérò pé àwọn oyin á tiẹ̀ máa pòòyì lórí obìnrin náà ni, pẹ̀lú ọbabìnrin lẹ́nu iṣẹ́. Ó ń mọ̀lára bíi wípé wọ́n jọ pín inú oyún ni, tó kàn jẹ́ pé ọdún bí ọ̀nà mẹ́wàá ló là wọ́n láàárín, àti ọ̀rá oyin pẹ̀lú DNA kannáà àti ìtẹ̀lẹ̀ inú oyún.

*Grace Jones* ni wọ́n wí. *Grace Jones.*

Ó tún àwọn ọ̀rọ̀ yìí sọ sókè, ó ń gbádùn bí wọ́n ṣé ń yí lórí ahọ́n ẹ bí ẹ̀rọ afọṣọ ṣe ń yí, nígbà tí Carla àti Dorian ń ṣe pàṣípààrọ̀ skurudẹ́rẹ́bà fún àwọn ohun ìṣeré Power Ranger tó ń jagun ní pátúwà. Fọ́rán ìwòran fò sókè, ó mì, àwòrán ibẹ̀ pòórá. A ti mú Grace wá báa níbẹ̀ lórìi ààmì láti Jupiter. Ó gbá irin àfaṣọkọ̀ tó wà nílẹ̀ lẹ́yìn TV mú, ó na ibi kíká orí ẹ̀, ó sì fi sí inú iho ééríà tẹlifíṣàn. Àwòrán náà padà. Grace ti lọ, a sì ti fi ètò lórìi irú mílíkì títà kan tó

ti bàjẹ́ dípò ẹ̀. Ọkàn ẹ̀ rẹ̀wẹ̀sì, ṣùgbọ́n àwòrán Grace ti jó sí inú orí ẹ̀ àfi bíi irin gbígbóná ìlọṣọ. Ó sáré lọ sínú yàrá màmá ẹ̀, ó ṣí àwọn àpótí aṣojúlóge ẹ̀, ó ń wá nǹkan láàárín àwọn ìtọ́tẹ̀, ó ń pòṣé. Ó ṣí àpótí aṣọ ẹ̀ pẹ̀lú agídí, àwọn dígí inú ẹ̀ ṣì sọọ́ di púpọ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀. Ó koríbọ̀ọ́. Nínú òkùnkùn, ó gbọ́ dídún fífò kan. Oyin kan pẹ̀lú ẹnu pupa bí ẹ̀rọ panápaná ń léfòó nínú ìtànná ariwo ẹ̀lẹ́tíríkì.

Sidra tapọ́npọ́n sínú ọkọ̀ takisí lọ sí East Dulwich, asọ òtútù Roland Mouret ẹ̀ tó ń tan yinrinyinrin nínú alẹ́ tútù. Lọ́fíndà Yves St. Laurent ẹ̀ ń ta sánsán pẹ̀lú òórùn bíi dàrúdàpọ̀ kan. Aṣọ pupa ológbò aláràán tí kò lẹ́yìn tó wọ̀ lọ́wọ́rọ́, ó sì lọ̀lá lára ẹ̀. Nínú ìjókòó ẹ̀yìn, ó le rí orí ojú ẹ̀ nínú dígí ìwẹ̀yìn ọkọ̀; ẹ̀yìn àti ẹ̀gbẹ́ kúkúrú, kò sí wàhálà, ó ṣeé mú jáde. Oun kan tón mì jolojolo lára dígí náà ni àtùpà oníwúrà kan tó dàbí ti Aladdin. Ó rì lọ sínú àga bí ìlú náà ṣé ń jádewá, pẹ̀lú ìka tó ń tọpinpin gbogbo oun tó le ṣẹlẹ̀ nínú òkùnkùn biribiri; ó ń ro bíi kí àtùpà yìí máa da epo bẹntiróò sínú etí aṣọ tó ti pinu láti má wọ̀. Ó tẹ fèrèsé ọkọ̀ sílẹ̀ bí awakọ̀ ṣe ń sọ̀rọ̀ láìdúró nípa jíjẹ́ ọ̀dọ́mọkùnrin ní Damascus. Atẹ́gùn tútù ń jáa lára jẹ. Ó dijú ẹ̀, tí gbogbo bótòbótò awakọ̀ náà ń wọ̀ọ́ lára láìjanpata. Kò tîì lọ sí East Dulwich fún ọdún díẹ̀. Kò tîì lọ láti ìgbà tó ti ṣiṣẹ́ fún ilé-iṣẹ́ atẹra-ìṣègùn alágbèéká kan fún ọ̀sẹ̀ kan. Níbi iṣẹ́ kìnní yìí, ó rí ọkùnrin pẹ́lẹ́ngẹ́ onígòlójú kan tí ò ga jù tó ń fomiwọ́n àwọn ewé níta ilé ńlá kan nínú aṣọ ilé sílíkì tó dà bíi kimono. Ó ń fọwọ́ tún ìgò ojú tó bà sórí imú ẹ̀ ṣe lemọ́lemọ́ lọ́nà tó fihàn pé ó ti mọ́ra. Ilé náà dàbíi àwòrán tí a mú wá láti Wallpaper Magazine; ohun ọjọ́ iwájú tó dàbíi pé kò jọ mọ́ àdúgbò yẹn tó ní ewé àti ìbàlẹ̀-ọkàn. Ó fi ẹ̀rọ abomiwọ́nlẹ̀ sílẹ̀, inú ẹ̀ dùn láti rí arábìnrin yìí, ó nawọ́ sí ìlẹ̀kùn iwájú ilé tó wà ní ṣíṣí. Wọ́n wọlé lọ. Nínú ilé, ó pòórá fún bí ìṣẹ́jú kan, ó sì padà pẹ̀lú ìnura lọ́wọ́. Ó fún-un ní ìnura, ó sì pàṣẹ fún-un láti lọ pààrọ̀ aṣọ nínú balùwẹ̀ tó wà nísàlẹ̀ níwájú; á san £150 fún ìtẹra-ilera fún ogójì ìṣẹ́jú aláìwọṣọ.

Ó gbáradì. Pẹ̀lú pátá dúdú tó wọ̀, ìbọ̀sẹ̀ alásẹ́, asaṣọrọ̀, àti ìborùn onífàdákà, ó gun pèpéle àjà lọ sókè níbi to ti ríi nínú aṣọ èmù yòròyòrò nínú yàrá ńlá, pẹ̀lú abọ́ ìpara tó dúró lóríi

tábìlì ẹ̀gbẹ́ ibùsùn kékeré tí a fi ìfẹ́ gbẹ́. Wọ́n jìjàkadì fún ìṣẹ́jú mẹ́wàá. Lẹ́yìn èyí, ó fi ìpara yìí yíi lójú, ó ń yán orí ẹ̀ sílẹ̀ sínú pọ̀tọ̀pọ́tọ̀ funfun tó wà lóri ilẹ̀ pákó, ó fagídí múu láa.

Lẹ́yìn èyí, lẹ́yìn tó ti bọ́ gbogbo aṣọ ẹ̀ tán lórí ibùsùn, tí ìmọ́lẹ̀ ń pín yẹ́lẹyẹ̀lẹ sórí àwọn ọ̀ṣọ́ orí àjà, ó báa fọwọ́ tẹ ẹ̀yìn onírun ẹ̀. Ó ń dún, ó ń yìn-ín fún bí ọwọ́ ẹ̀ ṣe lọ́wọ́rọ́ tó.

Iná ẹ̀ tó ń jó fún ọmọkùnrin yìí bẹ̀rẹ̀ nínú balùwẹ̀, níbi tí olùyàwòránilé ti jókòó lẹ̀gbẹ̀ẹ́ balùwẹ̀ pẹ̀lú ìborùn fàdàká ọmọbìnrin yìí lára ẹ̀, tó sì ń rẹ́rìín músẹ́ bẹ́ẹ̀.

Lọ́ṣẹ́ yẹn, àwọn iná nàà bẹ̀rẹ̀ sí ń jó ní yàrá ọ̀tọ̀tọ̀ nígbà kọ̀ọ̀kan; abẹ́ ilé, inú yàrá ìkàwé, yàrá òkè. Sidra ò lè gbàgbé ìkínní; kìmónò oní sílíkì tó ń fo yẹbẹyẹbẹ láti fi títóbi itan hàn, ìlà irun kan tó ń rá lọ sínú ìdí ẹ̀, agogo ẹyẹ agbe kan pẹ̀lú obìnrin kékeré kan tí ọwó ẹ̀ jẹ́ ọwọ́ aago, tí ẹnu agbe ẹ̀ ní màjàlà tó máa tàn ká, ìyàlẹ́nu ẹ̀rọ abomíwọ́nlẹ̀ tó ṣì ń yí lórí koríkò bó ṣe ń lọ, tó ń bomiwọ́n àwọn ẹyìn àṣírí ọ̀sán kó tó wọ inú ìdákẹ́jẹ́.

Ọkọ̀ takisí náà wọlé sí ẹnu ọ̀nà ilé ńlá Georgian náà. Sidra sanwó, ó tún fún awakọ̀ ní pọ́ùn mẹ́wàá síi fún àwọn ìtàn ẹ̀. Ó bẹ́ jáde, ó rìn kọjá lóríi pápá atẹ́rẹrẹ tí a kùn pẹ̀lú àwọn àtíbàbà funfun tí a da àwọn iná dákúdájí-yanranyanran bò, pẹ̀lú àwọn koríko òdòdó ti a gbẹ́ sí irú ère tó mú ẹ̀rọ̀ agégi dání àti èrè ẹ̀bí pẹ́pẹ́yẹ yìnyín ńlá tó ń na ọrùn wọn sí ara wọn, tí wọ́n ń yọ́ díẹ̀díẹ̀ sóríi koríko. Ó kanlẹ̀kùn. Ẹnìkan tó dàbí Marilyn Monroe ṣíi, tó sì wọṣọ ẹkùn adánilọ́rùn aláwọ̀ búlù àtijọ́.

“Káàbọ̀!” Ó pariwo pẹ̀lú ọ̀yàyà. “O gbayì o.” Ó fikún-un, ó sì sún s’ẹ́gbẹ̀ẹ́ kí Sidra lè wọlé. Atẹ́gùn tó lọ́wọ́rọ́ ń rùn síi bí oun ìpara ìfárungbọ̀n olówó iyebíye, ìpanu oníyẹ̀fun ẹlẹ́ran, tùràrí. Ẹ̀ṣọ́ ilé nàá kò wọnilójú rárá, pẹ̀lú àwọ̀ aláràbarà díẹ̀díẹ̀ níbí-lọ́hùún. Sidra gbé orí ẹ̀ sókè. Àjà mẹ́ta ló wà níbẹ̀, bó ṣe ríi sí. Ọpọ̀lọpọ̀ ẹran ara wà ní gbogbo àyíká, tí wọn ń faragbára, tí wọ́n sì ń yọ̀rọ̀ jáde àfi bíi pé wọ́n ṣẹ̀ṣẹ̀ kó wọn jáde ni láti inú agolo ńlá pẹ̀lú epo àti ọ̀rá bíi saccharine lára wọn, tí etí agolo tó mú tó tún wà ní ṣíṣí lókè so mọ́ wọn lórí bí wọ́n ṣe ń rìn lọ. Ó bọ́ aṣọ òtútù ẹ̀, ó fi kọ́ apá ẹ̀ bí ẹnìkan tó jọ Rod Stewart ṣe súnmọ́ọ láti gbàá. Ó kọ̀, ó ń wo ẹ̀yìn ẹ̀ lọ sí àtẹ oúnjẹ ìpanu tí ẹnìkan tó dàbí Pee-Wee Herman nínú

aṣọ iṣẹ́ aláwọ̀ eérú, bàtà funfun, àti táì kékeré pupa ń pín káàkiri. Ó yẹ àwọn àlejò yìí wò. Kò sí ènìyàn dúdú kankan níbẹ̀. Kò tiẹ̀ pinnu láti pín oúnjẹ ìpanu kankan. *Fìyẹn sílẹ̀ jàre*. Ó ti mọ́ọ̀ lára láti máa jẹ́ obìnrin dúdú kan ṣoṣo tó farajọ ẹlòmíràn nínú irú àpéjọ yìí, àfi tí Tina Turner bá yọjú, láti gba gbogbo atẹ́gùn àti ojú ìwòràn kúlò lọ́wọ́ ẹ̀. Tina ò sí níbẹ̀. Olúwa ṣeun.

Marilyn Monroe ti báa fẹ̀lẹ̀ gba ife ọtí wáìnì funfun kan. Ó mú ife onífèrè oníhò kékèké. “O jọọ́ ganni.” Sidra sọ ohun tí gbogbo afarajẹlòmíràn máa ń fẹ́ gbọ́.

Marilyn rẹ́rìín músẹ́. “Ọkàn mi fò f’áyọ̀,’ ó dáhùn bí ẹni tó n sé èémí lọ́nà tó jọ ti ẹni tó ń farajọ. “Luigi ṣẹ̀ṣẹ̀ kọjá sínú yàrá kejì yẹn ni.”

Sidra tẹ̀lé ohun dùùrù lọ sí ọ̀dọ̀ Luigi, agbàlejò wọn, onísinimá ọlọ́yàyà kan tó kúrú, tó ń pá lórí, tó kó ẹ̀gbà ọnà sára, tó sì jẹ́ kí oun tí a ń pè ní ‘tóbi ju t’ayé lọ’ kéré níwájú ẹ̀. Níbi tó ti ń ṣe ayẹyẹ òpin ọdún, ó jókòó níwájú dùùrù dúdú kan láàárín àwọn Venus mẹ́ta tó ń fún-un ní ẹja sálúmọ́nù tí a fi kírímù sórí ẹ̀ lóríi ìpanu kékèké oníyẹ̀fun. Inú ẹ̀ dùn bó ṣe ń nawọ́ síi. “Súnmọ́ mi níbí, ọmọ́ge!”

Ó gbà àwọn bọ́tìnì dùùrù mọ́lẹ̀ pẹ̀lú ipá. Àwọn èrò kan ṣùrù bòó. Sidra fọwọ́ fa apá báàgì ìléwọ́ ẹ̀ lókè èjìká ẹ̀. Àwọn èrò kékeré yìí ń pariwo, láì fún ara wọn ní ijánu kankan láti fọwọ́ kàán, láti ṣàròyé lórí ara wọn.

Ó rẹ́rìín músẹ́ ní apá ibi tó wulẹ̀ jẹ́ ayẹyẹ, ìdánilárayá. Apá ibí yìí ti máa ń dùn mọ́ọ̀ nígbàgbogbo. Àwọn ẹran ara yìí tẹ̀ súnmọ́ọ̀, wọ́n ń di ife wáìnì wọn mú. Olùyàwòránilé farahàn lẹ́yìn wọn pẹ̀lú skurudẹ́rẹ́bà méjì onídìí aláwọ̀ òfefèé lọ́wọ́. Ahọ́n púpọ̀ wà nínú fèrè ọtí wáìnì, wọ́n ń léfòó, wọ́n wá ń kájọpọ̀ láàárín ariwo yeye, kí wọ́n tó rì sí ìsàlẹ̀. Sidra di ojú ẹ̀ fún ìgbà kékeré bí kíkùn inú ọpọlọ ẹ̀ ṣe bẹ̀rẹ̀. Ó pòórá sínú ipò ẹ̀: Grace Jones.

Oṣù díẹ̀ sẹ́yìn, wọ́n ti ṣe ayẹyẹ mìíràn, èyí oníbòjú ní Paris, nínú ilé ìkóunọnàsí àtijọ́ lórí ààlà ilẹ̀ ti Champs-Elysees. Torípé ìdúnàádúrà ló bá wá, Hassan ti sọ fún-un pé òun lè má wá síbẹ̀. Báyẹn ló ṣe máa ń yẹra. Ọ̀un kìí mọ ìgbà tó máa dé láti wá fi ojú òréré àti àfiyèsí

wo oun tó ń ṣẹlẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí ẹni tó ni ilé iṣẹ́ náà, kò ní láti ṣe bẹ́ẹ̀; nígbà kọ̀ọ̀kan, ó farahàn láti jẹ́ kí àwọn afarajẹlòmíràn ẹ̀ máa wà nínú ìfura.

Ó ti kúrò lọ́dọ̀ àwọn èrò tó ń mìlẹ̀ngbẹ̀, ó ń wá ọ̀nà ẹ̀ lọ láàárín àwọn yàrá oníṣekúṣe títí tó fi wọnú ìkan lẹ́yìn ilé. Àwọn ojúlówó ìṣẹ́ àwòrán ọlọ́pọlọ rọ̀ sára ògiri, pẹ̀lú àpótí gíláásì tó kún fún ẹja oníràwọ̀ olóṣùpá tó ń mì lọ́nà onírẹ̀lẹ̀ nínú omi tí a tanná sí. Pósí kan tó jìnkòtò, to sì jẹ́ ti Íjíbítì tí a fi wúrà mú létí, wà ní ṣíṣí. Ó ti ń fi ọwọ́ ẹ̀ pa ibi iṣẹ́ ọnà yìí nígbà tó nípa ọwọ́ kan lẹ́yìin ẹ̀, ìka kan tó ń yípo ní jẹ́jẹ́. Nǹkankan nípa ìfọwọ́kàn yẹn dàbí oun tó dámọ̀. Ó fara mọ́ọ̀ láìlágbára láti kọ àyípadà kan tó ń ṣẹlẹ̀ nínú ikùn ẹ̀.

“Hassan?” Ó kọjú sẹ́yìn. Ọkùnrin náà ò sọ̀rọ̀. Ó wọ ìbòjú oní fàdákà tí a fi iṣẹ́ ọ̀ṣọ́ púpọ̀ ṣí. Kò sí ọ̀nà tí a fi lè rí ojú ẹ̀ wò. Ó wọ aṣọ iṣẹ́ aláwọ̀ búlù òru tí a fi àrà rán, tó sì bá àwọ̀ ẹ̀ mu; ó rán-an létí nípa Hassan. Ó wà ní ìwọ̀n gíga kannáà, pẹ̀lú ìdúró àti títínrín, ó tún jọ ọmọ Arábù. Ó ní irú irun alágídí kannáà. Òórùn bíi sìgá Kúbà àti ògógóró ni ó ń jáde láti ara ẹ̀. Ó ní irú ìtànná ẹlẹ́rìín kannáà nínú ojú ẹ̀. Dípò kó dáa lóhùn, ọkùnrin yìí gbàá lọ́wọ́, ó darí ẹ̀ lọ sínú pósí aláṣọ sílíkì yìí. Ó fọwọ́ sí abẹ́ aṣọ àríyá ẹ̀ tó jẹ́ àwọ̀ alámọ̀, ó sì bọ́ pátá ẹ̀. Ó fẹ̀ ìdí ẹ̀, ó sì sin ahọ́n ẹ̀ síbẹ̀, tó ń láa tó sì ń fáàmu pẹ̀lú ojúkòkòrò; ó ń dún bí ahọ́n ẹ̀ ṣe ń pòòyì, fi gún, àti dó ihò ìdí ẹ̀, àfi bíi pé ìyẹn jẹ òdòdó jíjẹ. Ó dóo nínú pósí yẹn láì bọ́ aṣọ kan ṣoṣo. Wọ́n padàbọ̀ sípò, láàárín ìwọ̀n aṣọ tó yí wọn lára. Sidra fi àṣírí ẹ̀ hàn bó ṣe ń dà, láìmò bó ṣe jáde wá láti isá inú ẹ̀. Ọkùnrin yẹn ò mira, bíi pé kò tîì gbọ́ oun tóbìrin yẹn ń sọ. Bí wọ́n ṣe jáde kúrò nínú pósí, ìdákẹ́jẹ́ wọn di èdè tí wọ́n jọ ń pín lò. Ó fi ẹnu kòó lọ́rùn jẹ́jẹ́ kó tó kúrò. Àwọn ẹja oníràwọn olóṣùpá kúrò nínú ilé wọn, wọ́n sì léfòó wá sọ̀dọ̀ ẹ̀, wọ́n ń lo ìgbà tán.

Nínú ààyè gbàgede padà, ó wọ inú àwọn èrò tó ń gégèé lọ sí oríṣiríṣi ọ̀nà. Ọkùnrin yìí ti pòórá. Òun kọrí síta láti gbatẹ́gùn díẹ̀ lẹ́yìnkùlé. Ẹja oníràwọ̀ olóṣùpá wá di olú tó ń jábọ̀ lára ẹ̀.

Ọ̀ṣẹ̀ mẹ́ta síwájú ní London, Hassan pèé wá sí ìpàdé oúnjẹ ọ̀sán kan. Ó dùúnwò, nínú aṣọ iṣẹ́ aláwọ̀ ìrókò ti Ozwald Boateng pẹ̀lú ọlọ́rùun poló dúdú àti ṣòkòtò. Ó ní bó ṣe máa ń mú ìfúnniníṣẹ́ṣe dún bíi èròngbà lásán, pẹ̀lú ohùn tó máa ń jẹ́ kí ènìyàn mọ́ pé kò ṣeré rárá. Láàárín ọ̀rọ̀ ẹ̀, òún ti rí irú ìhùwàsí àìròtì lójú ẹ̀. Òun ti ń wo inú àpò ìléwọ́ ẹ̀ láti sanwó ìlàjì oúnjẹ. Ọmọkùnrin náà ń wòó bíi pé ó mọ̀ọ́ timọ́tímọ́. Èyí jẹ́ wíwò ológe tó lọ́wọ́rọ́, tó sì wá fún ìgbà bíntín, tó fi jẹ́ pè lẹ́yìn tó ti lọ tán, ó rò pé nǹkan tí òun kàn rò lórí ni. Lẹ́yìn náà, ojú ẹ̀ dúdú, gbogbo ara ẹ̀ sì kọ́rẹ̀lọ́wọ́. "Iṣẹ́ tí kò le ni. Kò sí bí o ṣe lè ti mu ọtí yó tó, kọ̀ láti tẹ̀lé ẹnìkankan tí oò bá mọ̀ jáde. Mi ò fẹ́ kú ikú ọkàn ríru láàárín ọgbọ̀n'jọ́ orí mi o. Kóo sì sá fún gbogbo àwọn nǹkan tó ní ẹ̀pà nínú. Kò bá ẹ lára mu. Rántí ìgbà tí ojú ẹ wú? O dàbíi abo eerin." Ó rẹ́rìín ìyàngì.

Sidra súnkì sínú bó ṣe ń ṣe ìrántí. Ní tòótọ́, ó rántí oun tó ṣẹlẹ̀ yẹn. Ọkùnrin yìí ti sọ fún-un nípa ìrìn àjò ẹ̀ sí Greece, iṣẹ́ tó ń ṣe láti pèsè fún àti láti darí ìtọ́jú àwọn aláìnílégbé níbẹ̀. Ó sọ̀rọ̀ pẹ̀lú ìgbónára fún ìgbà díẹ̀, ó sì ń sọ àwọn ìtàn apanilẹ́rìín nípa àwọn ènìyàn tó ti pàdé, papàá jùlọ àwọn ọmọdé, bí àwọn ibùdó náà ṣe burú tó, àti irú ìbáṣepọ̀ gidi tí wọ́n ṣẹ̀ láìbìkítà fún bí ipò wọn ṣe burú tó. Ọmọbìnrin yìí ò retí àti rírú ọ̀yàyà báyìí gbà lọ́dọ̀ ẹ̀. Òtítọ́ ni pé nǹkan kékeré ló mọ̀ nípa ẹ̀ yàyọ̀ sí ìbaṣepọ̀ iṣẹ́ tí wọ́n ní. Ó tiẹ̀ fura pé àwọn ìfihàn ẹ̀ẹ̀kọ̀ọ̀kan tó máa ń sọ síta jẹ́ oun tí ó mọ̀ọ́mọ̀ ṣe, bíò tiẹ̀ mọ ìdí ẹ̀.

"Ṣé nǹkankan wà tí o fẹ́ sọ fún mi bi?" Ó bèèrè. "Nǹkankan tí inú ẹ̀ ò dùn sí nípa iṣẹ́?" Ó rọ̀ọ́ jẹ́jẹ́.

Pẹ̀lú ọwọ́ kan nínú àpò Ilẹ́wọ́ ẹ̀, Sidra di ìgò tùràrí mú. Olùyàwòránilé farahàn, ó ń dúró lẹ́gbẹ̀ẹ́ Hassan pẹ̀lú èéfín tó ń jáde láti ara aṣọ ẹ̀. Àwọn irin iṣẹ́ ìyàwòránilé ẹ̀ ni ó kán lọ́wọ́ ẹ̀. Àwọn ìka Sidra ń gbọ̀n.

"Mo ní láti lọ." Ó dìde lójijì, lọ́nà tó fi ti abọ́ kan tó ní àjẹkù ẹyin díndín nínú ṣubú. Ó bẹ̀rẹ̀ sí ní kó owó láti inú àpò ìléwọ́ ẹ̀. Hassan lejú.

Ó fi àpò ìléwọ́ ẹ̀ sílẹ̀.

Marilyn Monroe fakọ rìn kọjá, ó ń gbé àtẹ wàrà búlù oníkólóbó dání. Sidra mú ìkan lẹ́gbẹ̀ẹ́ ìpele àjà, ó jùú sẹ́nu; ó gbádùn adùn ẹ̀ láti tẹ èébì tó ń dìde nínú ikùn ẹ̀ rì.

*Iná tó bẹ̀rẹ̀ gbogbo ẹ̀ jẹ́ ìṣèèṣì, bí wọ́n ṣe sọ fún-un. Lọ́jọ́ yẹn, ìyá ẹ̀ Marianne, lẹ́yìn tó ti pààrọ̀ àsìkò iṣẹ́ pẹ̀lú ará ibi ìṣẹ́ ẹ̀ kan, padà sí ibùgbé ẹ̀ nírọ̀lẹ́. Torípé ó máa ń gbàgbé kọ́kọ́rọ́ ẹ̀ ní ọ̀pọ̀ ìgbà, ó tẹ agogo ẹnu ọ̀nà, ó fẹnukò wọ́n lẹ́nu, ó bá Carla àti Dorian wí fún àwọn oun ìfiṣeré Ninja Turtle tó dà káàkiri ilẹ̀ inú ilé, ó ń gba ẹ̀gbẹ́ Sidra kọjá nínú ilé ìdáná níbi tó ti ń yẹ inú kọ́mbọ́ọ̀dù wò, pẹ̀lú èròjà oúnjẹ tó tẹ́rẹrẹ sóríi tábílì. “Mo lérò pé o máa jẹ ju kéèkì fún oúnjẹ alẹ́,” ó sọ, pẹ̀lú ẹ̀rín músẹ́, kó tó bọ́ aṣọ iṣẹ́ nọ́ọ̀sì ẹ̀ tó sì rá wọ orí ibùsùn. Lórí tábìlì ilé ìdáná, Sidra kọ àwọn oun kékeré kan sílẹ̀. Vanilla extract wọn ti tán, ìyẹ̀fun ò tó, ṣúgà ìṣekéèkilọ́ṣọ̀ọ́ ti tán. Ó wọ aṣọ òtútù , pẹ̀lú bàtà eré. Ó ti ilẹ̀kun fúláàtì ẹ̀ lẹ́ẹ̀mejì pẹ̀lú kọ́kọ́rọ́ ẹ̀, bó ṣe máa ń ṣe tó bá ní láti jáde wéré, táá fi àwọn àburò ẹ̀ nìkan sílẹ̀ nílé. Ilé àjà agbénigòkè ń rùn fún ìtọ̀ àti òògùn, ó sì ń dún látòkè títí dé ìsàlẹ̀ àjà mẹ́rìnlá, ó ń gbọ̀n àfi bíi pé ó máa bìí síta ju ìta ilé lọ ni. Ó jáde kúrò nínú è, pẹ̀lú ìrántí pé ó ti ti ewé fàdákà ìpóúnjẹ jábọ́ sílẹ̀ ilé ìdáná, ó tún fi ilẹ̀kùn fíríjì àti kọ́mbọ́ọ̀dù sílẹ̀ ní ṣíṣí, Carla àti Dorian ń sàríyànjiyàn nípa bààlú ìṣeré kan tó ti bàjẹ́. Á rántí àwọn oun yìí t’ó bá yá. Ó ti wọ̀n wọ́n lọ́wọ́ ẹ̀, wé wọn sínú ewé fàdákà ìpóúnjẹ, gbé wọn gba inú iho àyà ẹ̀ tó ń fẹ̀ síi, ó sì tún ń wo ìwọlé wọn l’ayìíká, pẹ̀lú ẹ̀jẹ̀, pẹ̀lú ìbaninípòjẹ́ pẹ̀lú gbogbo ìdáàbòbò péréte tí wọ́n ní.*

*Vanilla extract ló dáa dúró. Wọn ò níí níbìkankan ládùúgbò mọ́. Ó ní láti rìn lọ sí sanwó-o-gbà tó wà nísàlẹ̀ títì kó tó rí ìgò kan rà. Ìṣẹ́jú ogójì péré ló gbà kó tó sọ gbogbo ẹ̀ nù. Ó padà dé láti rí gbogbo ilé ẹ̀ nínú èéfín. Iná náà burú jáì. Àwọn èèyàn ń fò jáde láti ojú fèrèsé àwọn àjà ìsàlẹ̀; wọ́n ń ju àwọn ìkòkó jáde pẹ̀lú aṣọ ìbora; wọn ń lo aṣọ ìtẹ́lẹ̀ ibùsùn bíi okùn tí kò gùn tó. Bí iná ṣe ń ta sókè, ìpariwoyeye soó níkùn pọ̀. Ó da gbogbo oun tó lọ rà sókè, ìṣekéèkilọ́ṣọ̀ọ́ tó ti màjàlà nítorí èéfín, ìgo vanilla tó ń mí èéfín sókè, ìyẹ̀fun tó ń dàbo gbogbo igi, fèrèsé, àwọn ọwọ́ lórí ọrùn ọkọ̀, àwọn ìka tó ń gbá ibi ìtanná ọkọ̀ dípò kọ́kọ́rọ́.*

*Kò ṣe pàtàkì irú oun tó ń ṣẹlẹ̀ níwájú ẹ̀ tó kánlù láìròtẹ́lẹ̀ yìí, ìyá ẹ̀, Carla àti Dorian ti wà ní ìsémọ́lé. Iná náà ń jó lọ. Ọmọ ìyá ẹ̀ ọkùnrin àti obìnrin kú sí ọwọ́ ìyá ẹ̀. Láìlágbára, Sidra ti dúró sóríi pèpéle, ó ń wòkè, ó ń kígbe, bíi ọmọ ayò àkánkù kan tó ń léfòó láàárín panápaná, okùn afami, àti èrò.*

*Ó ti ti ẹbí ẹ̀ mọ́lé láti dáàbò bò wọ́n. O ti ti ẹbí ẹ̀ mọ́lé, ó dẹ̀ ti pa wọ́n. Ara ìrántí yẹ máa ń parapọ̀ sínú àtubọ̀tán kannáà ni. Ó wá mú àwọn kọ́kọ́rọ́ jáde, tí ọwọ́ ẹ̀ sì ń gbọ̀n pẹ̀pẹ̀, ẹnu ẹ̀ ń kálòlò ìyá, kéèkì, fíríjì, ilé àjà agbénigòkè, aṣọ iṣẹ́. Ó gbìyànjú láti fi kọ́kọ́rọ́ sínú orúkọ wọn bíi pé wọ́n jẹ́ ìlẹ̀kùn tó máa ṣí, tó máa paradà di èèyàn síi lọ́wọ́ kó baà le mí lẹ́ẹ̀kansíi. Dípò èyí, àwọn kọ́kọ́rọ́ há, ó ń kọ̀ láti yí. Wọ́n há sí gbogbo ọ̀nà, gbogbo ààyè láti jàjàgbara. Ní àwọn ọdún tó tẹ̀lée, Sidra á pàdé àwọn oun tó ṣe lọ́jọ́ náà lẹ́ẹ̀kansíi àti lẹ́ẹ̀kansíi. Olùyàwòránilé bẹ̀rẹ̀ sí farahàn.*

Ayẹyẹ ọ̀hún tẹ̀síwájú, pẹ̀lú ẹranko tí ọwọ́ ò ká tó ń yọ oríṣiríṣi orí bójú ọ̀run ṣe ń tẹ́ rẹrẹ. Pee-Wee Herman kúnlẹ̀ lẹ́nu ọ̀nà ẹ̀yìnkùlé, ó ń mu Dom Perignon láti inú bàtà ọkùnrin mìíràn. Luigi ti pòórá láti inú àjọyọ̀ tiẹ̀. Onídán onírun fàdákà kan nà gbalaja sórí dùùrù, ó ń yí ara ẹ̀ lóbìrípo àràmọ̀ndà bí táì ọrùn tó tàn yoyo ṣe ń ṣàn jáde láti ẹnu ẹ̀. Àwọn èèyàn kan ń mu kokéènì lóri ìpele àjà, nínú ilé ìyàgbẹ́, lóri pàkó ìkónjẹsí. Nínú balùwẹ̀ ìsàlẹ̀ ilé, àwọn ara wà nínú balùwẹ̀, ère oníke tí a wọṣọ fún ń ṣẹ́jú nínú ìmọ́lẹ̀ tó panilára, wọ́n ti sùnlọ nítoríi iṣekúṣe àti àṣjù wọn. Àwọn kan wà tó ń dó ara wọn lábẹ́ àtíbàbà lóríi pápá, tí atẹ́gùn tútù ń kun ara wọn, tí àwọn ìmọ́lẹ̀ ọ̀ṣọ́ ń mì jolojolo àfi bíi pé ó ń sọ fún wọn pé àtíbàbà ọ̀hún máa ṣubú lulẹ̀, súnkì wọnú àwọn ara yìí gẹ́gẹ́ bí ara eré wọn.

Nínú ilé ìdáná, Sidra rò nípa àwọn oun èlò mímú tó bá ara wọn wọ inú ayé ẹ̀, bí wọ́n ṣe ń kú sí ẹran ara ẹ̀. Ó nawọ́ láti mú èso púlọ́mù kan láti inú abọ́ èso lórí pèpéle marble island aláwọ̀ eérú. Dípò ààrín gbùngbùn, nínú ojú inú ẹ̀, èso náà ní àwọn ìgò kékeré pẹ̀lú egbògi vanilla dúdú tó n sun omi jáde fún ikú púpọ̀. Ó mú èso púlọ́mù ọ̀hún dáni sókè.

Olùyàwòránilé bù díẹ̀ jẹ níbẹ̀. Arábìnrin yìí bojúwo ààrín ilé. Àwọ ẹran ara pọ̀ láti ibẹ̀ dé ibi tí ìléwọ́ irin ti ń bọ́fọ ẹran ara ọ̀ọ̀nì, pẹ̀lú àwọn ẹnu tó ń dìmọ́ọ pẹ̀lú eyín tí a ti gbá yọ, àti àwọn ẹsẹ̀ tó ń jo òjìji orí omi. Olùyàwòránilé parí èso púlọ́mù yìí. Sidra gbé ọtí wáìnì mu lẹ́ẹ̀kansíi, ó wòkè láti rí àwọn ọnà tó wà lórí párá funfun, ó ń wá ẹnìkan láti fàá jáde láti inú ìdógùún, igi, irin, egungun, kó ṣe ìfàjáde tó máa yíi padà. Ó ríra ẹ̀ bí olófìfo. Irú ìran báyìí ti mọ́ọ lára, ó sì ń fi ara ẹ̀ mọ́ọ díẹ̀díẹ̀, bí aago t'án fi ń wọn ooru.

*Kí ilé gogoro ọ̀hún tó di ahá tó ti jóná, ilé ìtẹ̀wé àtijọ́ kan ló dúró níbẹ̀. Kí ilé ìtẹ̀wé tó dé, àwọn oun ìkọ́lé láti kọ́ọ ló wà níbẹ̀. Kí àwọn oun ìkọ́lé tó dé ibẹ̀, a rí olùyàwòránilé kan t'órúkọ ẹ̀ ń jẹ́ Alrik, pẹ̀lú ìran kan. Kí ìran ọ̀hún tó dé, a ní ìrìn àjò ewu kan láti kọjá Òkun Atilántíkì sí Ìlú Ọba pẹ̀lú ọkọ̀ ojú omi. Alriki ti fi ọ̀dọ́mọkùnrin kékeré kan sílẹ̀ lẹ́yìn àti ìyàwó ọlọ́yàyà, tí ìpinu láti darapọ̀ mọ́ọ ní Lọ́ndọ́nù gbée nínú jó nígbà tó ń wáṣẹ́. Ṣùgbọ́n ìyàwó àti ọmọ ẹ̀ ti kúkúu kọ́lẹ́rà nígbà tí wọ́n fẹ́ rìnrìnàjò kannáà, ìrìn àjò tí ó kún fún ebi, òùngbẹ ìmọ̀ àti ìyanu nípa àtubọ̀tán ayé ẹ̀ tuntun. Ara wọn jẹ́ fífọ́n sínú òkun ahóyaya tútù. Pẹ̀lú ìpòruru ọkàn àti ìbànújẹ́, Alrik lo gbogbo ìgbà láti mú àdánù ẹ̀ lẹ́rọ̀ nínú isà oògùn ẹ̀rọ̀ ní Lọ́ndọ́nù. Nínú ìkan nínú irú àwọn isà yìí ni àwòrán ilé atẹ̀wé yìí ti jáde wá síi, ilé tí àwọn ènìyàn yóò ti máa tẹ ìwé àìlópin, ilé tá ní ilé ìṣọ́ kan lókè, bíi ìdánimọ̀, tá jẹ́ ìnawọ́sí gbogbo ìrìn àjò ẹ̀ kààkiri àgbáyé kúrò l'Ámẹ́ríkà. Àwòrán náà jó mọ́ ìrántí ọkàn ẹ̀ lálẹ́ yẹn nínú isà ní Lime House, tó ń léfòó pẹ̀lú ìfẹ́ láàárín ìrú èéfín. Bíi oṣù kan síwájú, Alrik ríṣẹ́ kan nílé iṣẹ́ ìkọ́lé kan. Ó ṣiṣẹ́ látìsàlẹ̀ d'ókè. Ní ìgbà tí ilé ìtẹ̀wé yìí di kíkọ́ ní 1920, ó ti fẹ́ ọmọ olùtajà tí a ń pè ní Bethany. Wọ́n bímọ mẹta. Ó tẹ̀síwájú láti ṣe ìlànà fún àwọn iṣẹ́ mìíràn ṣùgbọ́n ilé ìtẹ̀wé yìí jẹ́ èyí tó jẹ́ ààyò ẹ̀ nítorípé èyí yọ síi nígbà tí ó wà nínú ìrora púpọ̀, tí gbogbo ìlà ẹ̀ pòórá sínú ẹ̀jẹ̀ ẹ̀, ní ìrántí ìyàwó ẹ̀ àkọ́kọ́ àti ọmọ ẹ̀ ọkùnrin.*

*Kó tó kú, Alrik dúpẹ́ pé ilé náà á gbẹ̀yìn ẹ̀. Ní 1970, ilé ìtẹ̀wé ẹ̀ tó rẹwà ni a fọ́ lulẹ̀, lẹ́yìn tí wọ́n ti lòó bí ilé iṣẹ́ ọnà fún ìgbà díẹ̀, wọ́n wá fi àwọn fúláàtì gogoro tó burẹ́wà kan dípò ẹ̀. Torí pé ó jẹ́ oun ajíǹde kúrò nínú eruku yìí, Alrik bẹ̀rẹ̀ sí rìn kààkiri láàárín àwọn ilé gogoro yẹn. Á wọ inú fúláátì àwọn èèyàn, ó ń mí sí ara ilẹ̀kùn ayanbúrẹ́dì wọn, àti orísun iná*

*ẹ̀lẹ́tíríkì. Ó ń wá àwòrán ara ẹ̀ tó ti jáde lọ nínú dígí wọn. Pẹ̀lú inúnibíni, ìbànújẹ́, ó ṣe àwọn ìjàm̀bá kékèké tí àwọn ará ilé náà máa rò pé àwọn ló ṣeé. Láìní ìtẹ́lọ́rùn, lẹ́yìn àwọn ọdún tó tẹ̀lée, ó bẹ̀rẹ̀ sí ṣètò ìjàm̀bá ńlá mìíràn tó bá òfò ẹ̀ bárajọ. Níbẹ̀rẹ̀, ó kọ́kọ́ ń ba àwọn wáyà inú lé yẹn jẹ́, ó rìí pé ilé àjà agbéniròkè bàjẹ́ nígbàkúùgbà, ó tún yọ ẹ̀rọ apanáilé sọnù. Nígba tó yá, ìwà ìkà ẹ̀ gbèrú síi. Olùyàwòránilé ń gbòòrò síi nínú inúdídùn ẹ̀ fún ìpanirun.*

Sidra ti pàdé Grace Jones gangan rí lẹ́ẹ̀kan, lẹ́yìn àríyá ẹ̀ kan ní Royal Albert Hall, níbi tí Grace ti pẹ́ dé fún wákàtí kan, bí àwọn èèyàn pàtàkì ṣe máa ń ṣe. Ó ti káa mọ́ etí ìtàgé lọ́nà ìwọlé ẹ̀yìn; ó ń jà fitafita láàárín àwọn ẹran ara mìíràn tó ń ṣe nǹkankannáà.

“Grace!” ó pariwo, tí inú dídùn ẹ̀ ń wọ̀ọ́ lára gidi. “Àwọn èèyàn máa sọ fún mi pé mo jọ ẹ́!”

Grace, tó wọ aṣọ ṣìfọ́ọ̀nù tó fún mọ́ọ̀ lára, tí a lè rí inú ẹ̀ láti ìta, pẹ̀lú bàtà ẹrẹ̀ tó d’órúnkún aláwọ̀ aró pẹ̀lú awò ojú oníranmẹ́ta, rẹ́rìín músẹ́, pẹ̀lú sùúrù. “Ọọ̀mọ́geee yìí, ṣíṣebí elòmíràn jẹ́ t’àwọn abọgibọ̀pẹ̀ ṣùgbọ́n bí áńgẹ́lì ológo nìwọ ṣe rí.”

Sidra rí Luigi to n yín ìkan lára àwọn Venus ẹ̀ lọ́rùn nínú ọgbà ìkọ̀kọ̀ tó wà lẹ́yìn ọgbà iwájú tó kéré tó sì rí déédé. Ó làájá. Venus ti rẹ̀wẹ̀sì débi pé kò tiẹ̀ lè jàjàgbara tàbí pariwo. Ẹsẹ̀ ẹ̀ kàn ń gbá gbálẹ̀ léréfèé ni. Nísàlẹ̀ aṣọ oníyanranyanran ẹ̀ pẹ̀lú ẹrọ̀fọ̀ ni a ìrù ẹja kan wà tó so mọ́ Ọgbà Édẹ́nì. Láìdúró dádáa, Sidra gbé aṣọ òtútù ẹ̀ sílẹ̀. Ó fò sórí Luigi, ó ń lùú látẹ̀yìn ẹ̀. “Fi sílẹ̀!”

Pátá Venus ti pòórá; àwọn egbò díẹ̀ ti ń yọ nítan ẹ̀. Fún ọkùnrin róndó kúkúrú, Luigi lágbára lọ́nà tó yanilẹ́nu. Bí ẹni tí a ò le dáa mọ̀ bí olùgbàlejò tí ó pàdé ní wákàtí díẹ̀ sẹ́yìn, ojú ẹ̀ kọ́rẹ́lọ́wọ́ pẹ̀lú ìwòo “Kóṣìdànù, aṣẹ́wó!” Bó ṣe ń yípo, ó fún Sidra lẹ́ṣẹ̀ẹ́ lójú láìmọye ìgbà. Venus tẹjú mọ ojú ọ̀run alẹ́ tí kò fẹ́ gbàálà. Sidra ṣubú sẹ́yìn. Atẹ́gùn kúrò lára ẹ̀. Orí ẹ̀ yípo; báàgì ìléwọ́ ẹ̀ fò lọ. Ó ń níran bí ìgò tùràrí náà ṣe ń yọ bọ́rọ́ bó ṣe ń mì. Ẹ̀jẹ̀ ń kán jáde láti

imú ẹ̀ sí ẹnu ẹ̀. Ojú ẹ̀ ń gbọ̀n pìpì. Oh wo aṣọ òtútù Roland Mouret ẹ̀, pẹ̀lú èrò ààbọ̀ pé kó paradà di oun tí a fi ń fò jáde nínú bààlù, tí eléyìí á jẹ́ oun ìmúnigbàgbé ńlá kúrò nínú agogo inú orí ẹ̀, tó dàbí pé ó fẹ́ fọ́ọ̀ lórí dànù. Lẹ́yìn èyí, àwọn afarajọra Grace Jones mẹ́rin mìíràn tí wọ́n wọṣọ bíi tiẹ̀ gangan. Gbogbo wọn kọwọ́ bọ inú pọ́ọ̀sì ẹ̀, fún oun kan tó máa ń tẹ̀lée káakiri ní gbogbo ìgbà; epo bẹntiróò nínú ìgò tùrarí, ọkàn ààyè tó ti domi. Olùyàwòránilé farahànpadà, gbogbo ọwọ́ ẹ̀ sì jẹ́ kìkì iná.

Iná tó wà nílé Luigi burú jáì. Ó dàbíi t'àwọn ìyókù. Ó gbé ilé tó fìgbà kan jẹ́ ológo púpọ̀ mì, ó ya wọ inú òrùlé ẹ̀. Ó ń bi èéfín dúdú, ó ń pọ àwọn ẹran ara tó ń pariwo sítia. Lórí pápá ìta, Sidra wúkọ́ láti inú èéfín tó wà nínú ẹ̀dọ̀ fóró ẹ̀. Luigi, tí èéfín ti gbéhánu, sáré jànnajànnà, bí ère fìrìgbọ̀n bí èèyàn, ó ń fẹ́ pa iná ara ẹ̀. Àwọn àtíbàbà funfun tí kò léèyàn nínú ń jóná; orí pẹ́pẹ́yẹ oníyìnyín ti yọ́ tán, tí èyí tó kù nípa ara wọn ti ń yọ́ díẹ̀díẹ̀ lọ́nà ẹ̀gàn; ọkùnrin ńlá t'án gbẹ́ pẹ̀lú ewéko ti sọ ẹ̀rọ agégi ẹ̀ nù. Ìbòsí àwọn ọkọ̀ agbáláìsàn àti ọkọ panápaná ń dún lókè réré.

Ẹnìkan tó dámọ̀ sáré súnmọ́ọ̀. Hassan. Ó rí báṣubàṣu, ó wà nípò ìpayà díẹ̀, pẹ̀lú ìwò ẹ̀dùn lójú ẹ̀. Ọkùnrin yìí tó máa ń rìn jẹ́jẹ́ nígbà gbogbo, tó máa ń wà lẹ́rọ̀pẹ̀sẹ̀ gbáa mú pẹlú ẹ̀rọ̀. "Olúwaṣeun o! Wọ́n sọ́ọ̀ lórí ìròyìn. Ọkàn mi wà lókè fún ìfòyà. Wàá fún mi légbò inú púpọ̀ kí n tó pé ọmọ ogójì ọdún o." Ó fọwọ́ bo ojú ẹ̀ tí wọ́n ti lùpa. "Ta ló ṣe eléyìí? Màá paá!"

Ó gbìyànjú láti sọ̀rọ̀ ṣùgbọ́n kò lè ṣeé. Oun tó fẹ́ sọ ni pé: ṣé kò s'ẹ́nìkankan tó gbọ́ bó ti ṣé ń pariwo sínú ni láti iye ọdún yìí ni? Ṣé kò sí ẹnìkankan nínú ilé ayé òṣì yìí tó lè mọ́wọ́ ẹ̀ lẹ́jẹ̀, kó kọwọ́ bọ̀ọ̀ nífun láti wá nǹkan ẹlẹ́wà onígun tó lè mú sókẹ̀ sínú ìmọ́lẹ̀ ni? Ṣé kò sí ẹnìkankan tó lè ríi pé ó pòórá sínú Grace Jones nítorípé ìrora,̀ ẹbi, àti ìdánìkanwà pẹ̀lú ara ẹ̀ le láti dánìkan gbé ni? Ṣé kò sí ẹnìkankan tó lè rán-an létí nípa oun tó fẹ́ràn jùlọ nípa wíwà láàyè nítorí p'ó ti gbàgbé ni? Ṣé kò sẹ́ni tó lè rí tinú ẹyin yòòyò tó ti sọnù séyìn ọkọ

takisí lọ̀sàán ọjọ́ olójò kan he, kó sì wá fifún-un padà gẹ́gẹ́ bí ẹ̀bùn ìbẹ̀rẹ̀ tuntun ni? Ṣé ẹnìkankan ò kàn le wà nípò jẹ́jẹ́ ni?

Ó fi ọwọ́ ẹ̀ sínú àpò aṣọ òtútù ẹ̀. Rìsîìtì kan fò jáde, ó jábọ́. Kò rántí ìgbà tó fi síbẹ̀ ṣùgbọ́n oun ló ní láti ṣe bẹ́ẹ̀. Pẹ̀lú ìyanu, ó ti yèbọ́ iná yẹn. Ó ti gbé àwọn oun abẹ̀mí inú ilé jáde tó farapamọ́ bíi rìsîìtì tó ti rún. Ó bẹ̀ èrè lọ́wọ́ ara ẹ̀ bóyá eléyìí á bí olùyàwòránilé nínú. Hassan mú rìsîìtì ọ̀hún dání, ó ń wo àwọn ipa mẹ́ta tó ti kọ sílẹ̀. Pẹ̀lú ìgbọ̀nrìrì, ó ń tẹjú mọ́ọ bíi pé ó mú abẹ́rẹ́ àdó olóró dání pẹ̀lú gbogbo ayé ní síso mọ́ọ. Ó fa rìsîìtì náà ya, tí gbogbo èérún ẹ̀ ń fò nínú afẹ́fẹ́ tútù bí iná ṣe ń jó yee lẹ́yìin wọn.

"Tí o bá ti ṣetán, sọ fún mi àwọn oun tí ẹ̀rù ti ń bà ẹ̀ láti sọ," ó gbàá lábàá. Ó bẹ̀rẹ̀ sí ní sunkún nígbà yẹn. Òún dìímú, ó tẹ ẹnu ẹ̀ mọ́ ibi èémí ọrùn ẹ̀ àfi bíi pé ó jẹ́ ìrìn àjò ìmọ́lẹ̀, àfi bíi pé wọn á ti dé mercury kí wọn tó mọ̀. Ó so mọ́ọ. Wọ́n gbaradì fún bí ojú ọ̀run ti rí nínú pálápolo, fún ìkọsílẹ̀ olùyàwòránilé tó ń bọ̀.

———

Kọ́lá Túbọ̀sún is a Nigerian writer and linguist, author of *Edwardsville by Heart,* a collection of poetry. His work of translation, language and culture advocacy, creative and travel writing, and linguistics, have been widely documented. He lives in Lagos, Nigeria, and can be found on www.kolatubosun.com